# ELETI ỌFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 905 LAGOS SATURDAY 25 — JANUARY 31 1964 KOBỌ - MEJI


**Imale Kį Jo Bata:**

# Salamotu Feran Elede Se Sari F'oko L'Ebute Metta

**EBUTE-METTA**–Ko si'nkan ti ojukokoro ati ọkanjua ko ni da silẹ ni aiye ti a wa yi, iwa oju-kokoro na ni o mu awọn iyawo oniyigi lori kan ti nwọn fi nfi ẸRAN ẸLẸDẸ ti nwọn ri ko ni ifa se ọbẹ sari awẹ fun awọn ọkọ wọn ni awọn adugbo kan ni Ebute-Mẹtta ati agbegbe rẹ loru ijẹta.

Gẹgẹbi irohin oro na ti a ri gba lati ọdọ AYLIUKA onirohin wa lati ọja Sabo ati Oyingbo ni jẹjẹ ni awọn Oyinbo onisowo kan ti nwọn nta ẹran ẹlẹdẹ ati tolotolo ti nwọn ti pa pẹlu adiẹ ati ẹja fun awọn Oyinbo ẹlẹgbẹ wọn ti nwọn ko lewọ ẹlẹdẹ jijẹ, lọ da wọn nu sile ikolẹ kan leti ọja Oyingbo.

Awọn akowe-wolewole (Sanitary Inspectors) lati ibiṣẹ awọn onimọtoto ni nwọn paṣẹ fun awọn Oyinbo onisowo na wipe ki nwọn lọ ko awọn ẹran ẹlẹdẹ na sile idalẹnu, ki

(Wo yoku loju ewe kejọ)

## Eleyi Ara! Omo Odun Mewa Loyun Sinu

CHICAGO (U S A) —Ti ọmọ ọdun mẹtala ni a kọ gbọ, ewo ni ti ọmọ ọdun mẹwa ti a tun gbọ wipe o loyun sinu nilu awọn Oyinbo Amerika? Irohin ti a gbọ nipa ọmọ ilewe na ni wipe ọmọ ile iwe ẹgbẹ rẹ, ọmọ ọdun mẹrindinlogun ni o darukọ wipe awọn jọ ṣere pọ ki oyun to de.

Tisa ilewe wọn ni o kọ fura si ọmọdebinrin na wipe o loyun, o si sọ fun iya rẹ ti o ti kọ baba ọmọ na ti o gbe larede silẹ wipe o dabi eni wipe ọmọ rẹ loyun.

Dọkita ti nwọn mu ọmọ na lọ si ọdọ rẹ ni nitotọ ni, ṣugbọn iyalẹnu lo jẹ fun ọmọ paapa alara nigbati nwọn sọ fun un wipe a bi ọmọ, o ni ṣe kiṣe iru ọmọ-ṣere-ṣere ti nwọn nra fun on, ti on ma ngbe ṣere. Nigbati nwọn sọ wipe ọmọ totọ ni, nṣe ni o bu ṣẹkun.

Aiperi Wọrọ Awọn ọmọ Ẹgbẹ Alakukọ Ni Ibadan ... Nwọn yọ Agbeje ni Minisita.

(wo loju ewe kejọ)

AWỌN ARA ALAYABIAGBA NPALẸMỌ:

# Ara Olowogbowo E Ku Etigbo! Ijoba F'onte T'Oro Kereni Keji Lojo Satide

EKO—Alufa sọrọ, ojo ku, o ni Ọlọrun jẹri Ọrọ on ni ti irohin ti awa Eleti-Ọfe gbe jade ni ijẹjọ wipe Ijọba fẹ ko awọn ara Olowogbowo lọ si okun. Alasia nipa ilẹ wọn ti nwọn fẹ gba lati fi kọ kereni tuntun, gbogbo igbati ẹnyin ọkawe wa nka irohin na lọwọ ni Olotu Ijọba Apapọṣe, Ọlọla Tafawa Balewa ninu ile rẹ mba awọn ogunnagbongbo kan jiroro lori awọn ti nwọn ni lati gbe eto lati wole ti o wa lori ilẹ ti nwọn yio kọ kereni tuntun na le lọwọ.



Alhaji MUSA YA' DUA

Bawo ni ẹ ti ṣe eto kereni tuntun si o?

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ npa ipinnu ti wọn ṣe nibi ipade ti nwọn ba Ọlọla Tafawa Balewa nṣe, nwọn ni ọpọlọpọ awọn Oyinbo a-bani-kọle ni nwọn ti ndu iṣẹ folefole na wipe ki Ijọba gbe e fun awọn, sugbọn Ijọba fọnmu, nwọn ni awọn ibi iṣe eleto ilewiwo (LEDB) ni o yẹ ki awọn gbe e fun.

Onirohin wa ni on tun gbọ wipe ẹnikan ninu awọn ti nwọn mba Olotu Tafawa Balewa ṣe ijiroro lori ọrọ na ni ki nwọn fo re ki nwọn to gbe iṣẹ ilewiwọ na fun awọn

(wo oju ewe kejọ)

# Gatskell Memorial Foundation To Aid Commonwealth Students

LONDON- A national memorial to Mr. Hugh Gaitekell, former leader of the British Labour Party who died just over a year ago, will take the form of an educational foundation to provide scholarships for Commonwealth students in Britain and for British students to go the Commonwealth.

This was announced in London recently.

Leaders of the churches, all three political parties, the trade unions, the academic world and two big banks have put their names to the appeal, thousands of copies of which will be sent to prominent people everywhere.

The appeal says: "The death of Hugh Gaitskell has deprived our country, the Commonwealth and the world of agreat statesman, a man who could not ignore the challenge of public duty.

"The measure of his contribution to the solution of the economic, social and political problems of the 20th century has been universally recognised.

"His experience gained while working in the field of adult education made him a devoted advocate of greater opportunities for all, and he was a firm believer in the need to forge closer links between the peoples of all races.

"We feel that a memorial to Hugh Gaitskell should be a practical contribution towards these aims.

"It is proposed to establish an educational foundation for giving grants to students from the Commonwealth at British universities and colleges, both for academic and technical education.

"We also intend that the foundation should assist British students who go to Commonwealth countries to complete their training.

"The provision of such assistance will be a worthy memorial to a man whose life was dedicated to improving the lot of others.

"We confidently ask all who recognised the qualities of Hugh Gaitskell to subscribe generously to this appeal."


THE ANSWER TO TROPICAL CONDITIONS

★

UNMATCHED AFTER SALES SERVICE

★

MERCEDES-BENZ



LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT and ABA.


## Cleaning St. Paul's Cathedral

### (By BBC Correspondent)

LONDON—Seven million gallons of water were used in the recent cleaning of the great West Front and two towers of St. Paul's Cathedral in London, which has been accumulating grime in since Sir Christopher Wren built it 250 years ago.

Needles to say, some Londoners, affectionately attached to dark view of St. Paul's, protested that this face-wash could never have been intended. But as the director of the company in charge of the cleaning, Colonel Simpson pointed out in the BBCGeneral Overseas Service programme 'Here and Now it was reasonably to suporse that Sir Christopher Wren would not have chosen a white stone, like Portland, if he had meant the Cathedral to look black. In fact, there was evidence that he had himself made plance to have it cleaned for a service which Queen Anne was to attend, but whether this had been done was not known.

None of those modern products advertised as washing whiter than white' coulc be used on St. Paul's for chemicals of any kind, whether acids or alkalis, would badly affect Portland stone, which is a limestone. Pure cold water only was used, followed by rubbing down with a special type of wire brush and a form of sandstone called mason's gripstone, which breaks up and works off the dirt without damaging the stone.

Colonel Simpson commented on the remarkable good condition of the carving even about 200 feet up on the towers, despite exposure to wind and raid. Lower down, it was fascinatingly details, he said and among some interesting pieces now clearly revealed by the removal of the accumulated dirt were the heads of three cherubs over the Dean's door, on the outh side of the Cathedral. One of the three weeping and the tears are now once more sible.

Iwe Akoka Yoruba

# Awon Oruko Ti A Nje Ni Ile Yoruba

## (Lati Owo Alufa Atilade)

Ọmọ ti o wa ninu apo nigbati a fi bi i ní a npe ni Ọkẹ. Ọmọ ti o ba gbe ibi kọrun nigbaati a bi i ni a npe ni Aina tabi Ojo. Ọmọ ti a ba bi ninu apo awọ fẹlẹfẹlẹ bi ọkẹ ṣugbọn ti apo awọ na ti ya fun ara rẹ ni a npe ni Salakọ ti o ba jẹ ọkunrin. Bi o ba jẹ obinrin a npe ni Talabi. Ọmọ ti o ba dojukọ ilẹ nigbati a fi bi i ni a npe ni Ajai. Ọmọ ti irun ori rẹ ba ri mulọmulọ ti o si kako fun ara rẹ ni a npe ni Dada. Ọmọ ti 'o ba ni ika mẹfa lori atẹlẹwọ kan ni a npe ni Olugbodi. Ọmọ ti iya rẹ ku ni ọjọ kanna ti a bi ni a npe ni Jọjọ. Ọmọ ti bi nigbati iya ti di agbalagba ni a npe ni Ilọri. Ọmọ ti o ba kọ ẹsẹ rẹ silẹ dipo ori nigbati a bi i ni a npe ni Ige. Fun oriki diẹ ninu awọn ọmọ abamin wọnyi, a tọka nyin si inu Iwe Iwe "Akọka Yoruba Apa Kẹrin" labẹ ori ẹkọ "AWỌN ỌMỌ ABAMIN"

Awọn orukọ miran mbẹ ti nwọn nfi iṣẹ idile ti a bi ọmọ kan han: Apẹrẹ iru awọn bawọnyi ni orukọ awọn ti a bi ni idile awọn ti nlu ilu dundun tabi bata nwọn ama jẹ orukọ ti o bẹrẹ pẹlu Ayan bi Ayantọpẹ, Apankọṣọ, Ayanwunmi. Awọn ti nlu ilu Ṣẹkẹrẹ ama jẹ orukọ "Aje" bi Ajetuamọbi, Ajedapọ, Ajediwin. Awọn ti a ba bi ni idile Ọdẹ ama jẹ orukọ bi Ọdẹjide, Ọdẹwale, Ọdẹku, Ọdẹdiran. Awọn gbẹnagbẹna a ma jẹ Ọnadiji, Ọnayẹmi, Ọnadayọ.

( Wo yoku loju ewe kẹfa )

## Yigi Kobo Meje Fun Iyawo Apapandodo Ni Ilu Ilorin

ILỌRIN....Awọn enia ti awọn dongari Ọlọpa ko ninu awọn Obinrin Karuwa ti ko lọkọ tọ igba enia ni arin ilu Ilorin ni ijẹta lọ si agọ awọn Ọlọpa lati ṣe ikilọ fun wọn nipa awọn ọkunrin onibara wọn ti nwọn nyọ awọn ara ilu lẹnu.

( Wo yoku loju ewe kẹfa )

# Awon Olopa Mu Olofa Lo Si Ilorin Nitori Owo-ori

ỌFFA (lẹba Ilọrin — Oto adọta enia ti nwọn tẹle Ọba Ọlọfa Musitafa Keji ti awọn Ọlọpa Ilọrin wa mu pẹlu akọwe Olowo ori ilu Ọffa, Ọgbẹni Samu Ogunwọle ti nwọnni ki nwọn wa sọ tẹnu wọn nipa owo-ori kan ti nwọn ni nwọn gba ti nwọn ko fi jiṣẹ.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ nipa ọrọ na, Ọba Ọlọfa ni o iranṣẹ sọ fun awọn alaṣẹ Ijọba ibilẹ Ilọrin wipe awọn ko mọ ibiti adọta le nirinwo (£450) wọlẹ si ninu owo ori kan ti awọn akọwe olowo ori ilu on gba.

Gbara ti awọn alaṣẹ Ijọba ibilẹ Ilọrin ti gbọ ọrọ na ni nwọn ti sọ fun awọn Ọlọpa ọtẹlẹmuyẹ ki nwọn ba wọn tẹsẹ bọ ọrọ na ni kikun. Eleyi ni o jẹki awọn Ọlọpa wa si Ọffa lati wa mu Ọba Ọlọfa pẹlu Samuẹli akọwe olowo ori ati akọwe Kotu ibilẹ kan pẹlu iranṣẹ (messenger) wọn wipe ki nwọn wa sọ bi owo-ori na ṣe junu.

A ko ti mọ ẹjọ ti nwọn yio ba wọn ro, ṣugbọn awọn Ọlọpa ti ni ki nwọn wa enia ti yio duro fun wọn wa.

## Ejo Telo Olowo Ojiji Di Ganran

EKO–Adajọ Kotu awọn Ọlọpa l'Eko ti ni ki awọn ọlọpa gbe ẹjọ ọgbẹni kan ti o nṣe iṣẹ telọ ransọran sọ ti orukọ rẹ njẹ Yesufu Bakare Yẹkinni ti awọn ọlọpa ni on ati akowe Banki Adesina Willoughby ji owo gọbọyi kan gbe ni nu owo awọn Oyinbo onisuga ni Ilọrin, lọ si Kotu ganran.

Ni igbati awọn ọlọpa bẹrẹsi ro ẹjọ wọn ni iwaju adajọ kotu awọn ọlọpa, nwọn sọ bi telọ olowo ojiji na ti se mu owo kan lọ si ọdọ awọn Oyinbo onimoto ti o lo san owo asansilẹ fun moto ayọkẹle kan ti o ni on fẹ ra.

Awọn ọlọpa ro ẹjọ mọ Adesina Willoughby wipe on ni akọwe Banki ti o wa nidi iwe ti o ṣe iranlọwọ fun awọn ti o wa ji owo na gbe ni Banki l'Eko.

## English School Boys Make Implements For Bechuanaland

Three boys in the metalwork class of Rushcliffe County Technical Grammar School, Nottingham, central England work on trowel blades as part of their plan to help Swaneng Hill School Bechuanaland.

The English school, with 430 pupils, has „adopted" the African school following advice from the British Humanist Council, and the Boys are planning on providing money, books and equipment. Already the masters and boys have sent £250 direct to Swaneng Hill and they intend sending books, wall charts and class-room apparatus.

In the metalwork class the pupils are making hoes, rakes and similar small agricultural implements.



# ELETI-OFE

(ANJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMS
28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-OFẸ" LAGOS
B. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 985 SATURDAY JAN 25, - JAN 31 1964.


## ORO OLOTU:

# Wahala Yi Nko...?

Awọn baba wa ni ilẹ Yoruba fẹran lati ma fi owe yanju ọrọ ti o ba di koko pupọ, eyi n'i o m u wọn ti nwọn fi sọ wipe bi ina ko ba tan laṣọ ẹjẹ ki tan ninu eekan. Lati bi ogun ọdun sẹhin ni a w ọ n ara ilu Afirika ti aja fun ominira ilu wọn g b o g b o awọn asiwaju ilu kọkan ni nwọn ni awọn fẹ yọ ajaga kuro lọrun ara awọn.

Olukuluku wọn ni nwọn nsọ wipe awọn ti kọgbọn to lọdọ awọn Oyinbo awọn si le selu laisi wahala.

Bi a ba wo iwaju ti a si wo ẹhin ao ri w i p e awọn Oyinbo ọga wa ti ana na fa ọmọ yọ, nwọn fun ọpọlọpọ ilu Afirika ti o wa labẹ wọn na ni ominira wipe ki awa na ma ba iṣẹ Ijọba lọ sugbọn k o y e awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ rara nkan ti o de ti o jẹ wipe gbara ti nwọn ba ti fun wa ni o m i n i r a na WAHALA ti BẸRẸ niyẹn.

Nwọn ni bi oju ko ba ti ole, oju nti oninkan ti o nlọgun wipe ole gbe on ni nkan lọ lojojumọ.

Ko j u ọsẹ mefa lọ nisisiyi t i awọn Gẹsi fun ilu kan ti nwọn npe ni Zanzibar ni apa Ila Orun Afirika ni ominira wipe ki awọn na ma da eto Ijọba ilu wọn ṣe. Lọjọ ti o di oṣu kan ti ọwọ w ọ n ba eeku-ida ni nwọn le ọba ilu wọn kuro lori itẹ ti gbogbo nkan di rudurudu mọ wọn lọwọ.

A fi eyi ṣe apejuwe ni, melo ni ẹ o ka ninu ehin ẹnu Aderele. Olotu Ijọba ilu Tanganyika Ọgbẹni Julius Nyerere paapa ni lati sa kuro nilu rẹ ninu ọsẹ y i nigbati awọn ṣọja jagunjagun ilu rẹ fẹake kọri wipe onia-ro fun awọn oṣelu wọn.

Bi awọn nwọnyi ti nṣe eyi ni awọn miran npa ara wọn lori ala-ilẹ ti o wa lario wọn pẹlu awọn aladugbo wọn.

Ṣe ẹnyin na wa ri wipe wahala wa fun awọn oṣelu wa ti a wipe a nfẹ ominira.

# Iwe Si Olotu

## Olopa Feru Gbabukun

Olotu, ko ya mi lẹnu rara lati gbọ wipe awọn Ọlọpa kan nji iwe idanwo ra ki nwọn ba le di Ọga nibi iṣẹ wọn lọla.

Awọn Ọlọpa atijọ ni nwọn ti mọ nkan ti nwọn npe ni otitọ, otitọ ko si ninu iwa awọn ọlọpa ti Ijọba wa ngba sẹnu iṣẹ nisisiyi. Bi nwọn ba ri ole nwọn ko ni mu u, bi nwọn ba ri ibi ti olohun gbe nkan rẹ si, nwọn a ṣe atọka fun awọn ole ti yio gbe e ki nwọn le pin wọn nibẹ.

Ti o ba dabi irọ ni ọrọ ti mo nsọ ki ẹnyin na ma ṣe akiyesi irohin awọn ọlọpa ti nwọn nju sẹwọn lojojumọ. Ole ati ọkanjua pọ ninu wọn-gbogbo wọn ni nwọn fẹ kọ ile petesi nla ki nwọn si tun ra mọto ayọkẹlẹ.

Ẹ jọwọ, ẹ tubọ ba wa tuna aṣiri awọn ọlọpa ti nwọn feru gba ibukun nibi iṣẹ wọn.

Emi ni,
Surulere, John Adeboye
Eko

## A Fe Iranlowo Ijoba

Ẹ jọwọ Olotu, a fẹ iranlọwọ meji fun ilu wa, Sagbẹ lati ọdọ awọn alamojuto Ijọba apapọṣe ilẹ Nigeria, ekinni ni ti ọna oju mọto ilu na ti ko dara, ti o mbajẹ ni siko ojo. Bi nwọn ba le ba wa tunṣe, ki nwọn yọ ọda si i inu wa yio dun.

Ikeji ni ile igba egbogi fun awọn abiyamọ ti ko si nilu na, A fẹ ki Ijọba ki o ran wa lọwọ, ki nwọn jẹki a ni dọkita oniwosan kan ni agbegbe ilu wa na:

Olotu, Oluwa Ọba yio ma ran yin lọwọ, ẹ ṣe aye ti ẹ fun mi ninu iwe yin.

Emi ni,
R. A. Raimi Ajide
Eko

# The Late Chief S.O Shonibare's Estate Value Over £1m

Current rumour among local business men and overseas financiers is that the estate of the late S. O. Shonibare is worth over £1 million sterling in the present day market value.

The Late Shonibare who was 44 years of age before he died was poprietor of National Investment and Properties Company (owners of many buildings at Maryland Ikeja) and Managing Director of Amalgamated Press of Nigeria (publishers of the 'Daily Express.

He died in a London Hospital last Friday and his corpse was brought back to Nigeria by air and was buried at Ijebu-Ode his home town.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

## Lati Owo Ayiluka

### S. O. Shonibare

Oku di meji ariwo, ẹkun di pupọ; nkan ti o jẹki emi Ayiluka sọ bayi ni ti iku awọn ogunnagbongbo meji ninu awọn ọmọ Ẹgbẹ Oduduwa ti nwọn ku tẹle ara wọn ninu oṣu ti a wa yi — ikinni ni ti Alhaji Issa Akangbe Williams ti o jalaisi ni Olowogbowo l'Eko, ekeji ni ti ọbgẹni wa, Oloye Samuel Ọlatubọsun Shonibarẹ, ọga-agba ile iṣẹ ti nwọn ti nte iwe irohin ojojumọ ti nwọn npe ni DAILY EXPRESS l'Eko ti o jalaisi ni ilu Oyinbo (London) ni irọlẹ ijẹsan.

### Omo Obanta

Mo mọ Ologbe Shonibarẹ ko ju ọdun merindinlogun lọ nisisiyi nigbati a ṣẹṣẹ da Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa silẹ; ọga mi Ọgbẹni Bisi Ọnabanjọ ("Aiyekotọ") ni o mu mi mọ ọ. Nigbana akọwe ni o nṣe lọdọ awọn Oyinbo oniṣowo (UAC) l'Ẹhingbẹti ni Eko nigbana.

Olotu kekere ni mo nṣe ni ile iwe irohin "DAILY SERVICE" nibiti on na gbe wa di ọga ki o to jalaisi yi labẹ awọn Ọgbẹni bi Ọlatunji Idewu, Mobọlaji Ọdunewu ati Bisi Ọnabanjọ ni mo wa. Ninu oṣu ti o di ọga agba (Manager) ni abẹ awọn onisọwu U A C emi ni akọwe onirohin ti nwọn ran lọ sọdọ rẹ lati kọ irohin na ni ẹkunrẹrẹ, on na si gbadun mi daradara pẹlu irohin rẹ na ti mo kọ.

### Omo Abile Soro

Ni ile itaja Kingsway Stores ni mo ma nlọ pade rẹ ti ba fẹ gbọ ọrọ lẹnu rẹ nipa ọrọ ẹgbẹ Oduduwa ati ti awọn Youth Movement. Lẹhinti ma tun ni nkan pọ pẹlu ologbe na ni igbati mo pada sori aga pẹlu awọn ti a jọ nkọwe IROHIN YORUBA.

On alara paapa ni o pade mi ni Ibadan ti o ni on gbọ wipe awọn ni mo gbọ Yoruba daradara nitorina ki nwa pade on l'Eko lati ma ran awọn lọwọ ninu iwe irohin awọn.

Ẹnyin ọ'rawe mi, ṣe ẹnyin na wa ri wipe iku ni opin ero gbogbo wa? Bi a ni owo lọwọ, a o ku, bi a ko si ni owo lọwọ a o ku. Kinni wa ṣe wa ti awọn ẹlomiran sọ aiye di awalọ, ti nwọn ki fẹ ṣe nkan rere sinu aiye ki nwọn to lọ jẹ ipe Olodumare ẹlẹda wọn?

Ọmọ Ọbanta, Ọmọ abilẹ sọrọ kilẹ yanu, O digba o!

### Ara Olowogbowo

Mo gbọ owo gọbọyi nibọ fun awọn ara Olowogbowo lati ọdọ Ijọba fun ile wọn ti nwọn fẹ gba fi ṣe ọju ọna kereni tuntun. Owo ti nwọn fẹ gba ko ni o ndun mi bikoṣe ile awọn itan ti a le mọ fi pa itan fun awọn ọmọ wa ti nwọn fẹ wo kanlẹ.

Mo niran gbogbo ọdun igbati mo wa lọdọmọde ti temi pẹlu awọn Karamọ ma nwre kiri opopo Apoti tẹmi pẹlu awọn ... ọmọde awọn Savage pẹlu Ologbe Ben Joseph. ngbọn lọ ... ọmọde toto ... igbana nitoripe ko si mọto Aiye awa ... le ṣe wa iṣẹ bi ti aiye ode yi. ... ẹlẹ ti o ...

Ti a ba ku ... to ni Oke Olowogbowo o a gba eti ebute ... wo awọn ... pẹlu awọn Ẹgba ti Itọlẹ lọ lati lọ ... (cocoa) ati epo lati Abeokuta. Iyẹn nwọn wa ta ko ... gbata ati Alakoro fẹrẹ dinan nilu Eko ni wipe ọrọ Ẹk... ... kereni tuntun, ti nwọn ba kọ k...

### A Jayabiagba

Ọrọ ilẹ awọn ara Olowogbowo yi jẹki ntun ... ... ti Ijọba ha awọn ran ọrọ kan ti mo gbọ nipa ... laipẹ yi wipe ti ... ngbe APAPA ALAYABIAGBA ... awọn fẹ lo ki nwọn ko ẹru wọn jade nibẹ nitori ... Ijọba ko ti ilẹ ti nwọn ngbe na. Mo gbọ wipe ... wọn. ba wọn sọrọ lori owo ti nwọn yio fun ...

( Wo yoku loju ewe kejọ )



# Akoka Yoruba

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Lẹhin orukọ abiso, awọn Yoruba tun ni oriki ti a fi npe ẹnikọkan. Awọn ẹniti o ba sunmọ ni dada ni nwọn i mọ oriki enia ti nwọn si i ma lo o lati pe ni bi orukọ ifẹ, iyin ati iwuri. Oriki awọn ọkunrin yatọ si ti awọn obinrin. Diẹ ninn oriki awọn ọkunrin ni wọnyi:- Ajamu, Alamu, Ajagbe, Ajani, Akanbi, Alade Diẹ ninu awọn oriki obinrin ni 'wọnyi:- Ajikẹ Asunkẹ Atọkẹ, Abẹkẹ, Abikẹ, Arikẹ, Akankẹ, Aṣabi, Adunni, Abẹbi ati Ayọka.

Lẹhin oriki, awọn Yoruba tun ni orukọ Orilẹ ti a nfi nmọ iṣedalẹ idile ti kọkan wọnyi, a le tun gbogbo ọmọ Ilẹ Yoruba to ki a si mọ idile ti ẹnikọkan ti orilẹ wọnyi ni' wọnyi:- Iji, Ẹru, Ogun, Ọkin, Aro; Opo, Agbo, Ikọ, Agan,Ọgọ Ẹlọ Ẹgẹ Ọka Erin Agbe Ojo ati Ẹdu.

Ko si ọmọ Yoruba kan ti awọn yio ki oriki ori'e idile tirẹ t ori rẹ rẹ ko ni wu; nitorina o yẹ ki ẹnikọkan gbidanwo lati mọ oriki idile rẹ, ki o le mọ iru enia ti awọn iran na on ti jẹ. Onikaluku enia le kọ nipa oriki orilẹ rẹ lati ẹnu awọn onilu wa, tabi awọn asunrara tabi awọn ti npẹṣa ni Ilẹ wa. Fwọn Iya Agba wa mọ owọn oriki wọnyi, o si yẹ ki a kọ ọpọlọpọ nkan lọdọ wọn, ki nwọn tu fi aiye silẹ.

## Eleti-Ofe Daraba

DAGENITE
BATTERIES
give you a longer run for your money!




# Isele Nla Se Ni Ilu Formosa

FORMOSA- Gbogbo awọn ara ilu Taiwan ni iFormosa ni nwọn wa ninu jinni jinni ẹru nisisiyi lori iṣẹlẹ nla kan ti o ṣẹ nilu wọn loru Satide ijẹjọ ti nkan bi ọgọrun enia ku bamubamu, ti awọn ogunlọgọ enia si wa lẹnu nwọn yio ku tabi nwọn yio ye.

Gẹgẹbi irohin t i a gbọ nipa iṣẹlẹ na awọn ile ti o wo lulẹ nlọ bi mẹwa din legerin, awọn t i o s ọ di a l a p a jẹ ẹgbaa (2,000) awọn enia t i isele n a sọ di alarilegbe nlọ bi ẹgbẹrin )800) enia.

Nwọn ni ofo ti iṣẹlẹ na ṣe ni apa A r i w a ilu na awọn ko ti mọ sugbọn ti arin ilu n a n i eyiti awọn k a y i.

Onirohin wa tun fi ye wa wipe gbogbo awọn papanapana ilu na ni Ijọba pe sibẹ lati wa ran nwọn lọwọ nitoripe ọ r ọ iṣẹlẹ na kuro ni wasa nitoripe gbo gbo ọna reluwe ilu n a ni o bajẹ patapata, ti gbogbo irin kako.

Ni i l u Hongkong ni a tun gbọ wipe iṣẹle tun ṣẹ ni ọ j ọ Satide kanna, sugbọn a ko ti gbọ w i p e iṣẹlẹ na ṣe w ọ n lofo pupọ nilu na.

# Yigi Kobo Meje Fun Iyawo Apapandodo Ni Ilorin

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Ọrọ kekerẹ kọ ni kiko ti nwọn ko awọn obinrin ti ko lọkọ na nitoripe gbogbo awọn ọrẹ ati ọmọlẹbi wọn ni nwọn bẹrẹsi sọkun lojude awọn Ọlọpa nitoripe nwọn ko mọ nkan ti awọn Ọlọpa fẹ fi wọn ṣe.

Ni kukuru Ọga Ọlọpa ni awọn ti gbọ irohin wipe awọn karuwa yi ni a ngba awọn ọlọṣa ti nwọn nfọle kiri sile nitorina awọn pa a laṣẹ ki olukuluku nwọn lọ wa ẹniti yio so yigi fun wọn ni kiakia ki nwọn to ṣe ọdun Itunu-awẹ loṣu ti mbọ.

Akọwe onirohin wa ni awọn Ọlọpa ni ẹniti awọn ba ri mu ti ko lọkọ, ti ko si so yigi awọn yio le e kuro nilu.

# E Ma Ka Iwe Irohin Eleti Ofe Losose

Fun Irohin Aladun

# "Know Nigeria" Campaign For British School-children

LONDON:— Twenty-four British schoolchildren were welcomed to Nigeria House, London the other day, by His Excellency Alhaji Abdul Maliki, Nigerian High Commmissioner in Britain, when he launched a campaign to publicise Nigeria.

The educational campaign, "Nigeria Today", is designed to inform British boys and girls about most aspects of Nigerin life and affiars a spokesman for the High Commissioner told our correspondent.

School parties from secondary schools in the London area will be invited to vist Nigeria House to see films and discuss Nigerian affairs during the next few months. The first school to take part in the scheme was the South East London Secondary School.

"A new theatre for film shows has recently been completed in Nigerian House and the library attached to it contains authoritative and up to date films of an educational nature about Nigeria. These facilities have been brought to the attention of educational authorities," the spokesman said.

"The High Commissioner hope geography and history masters will recognise the value of this exercise as an aid in their class projects on Africa, and particularly Nigeria as an example of the emergent and stable new nations of the Commonwealth."

## British Firm Designs Special Equipment For Nigerian Farmers

LONDON- A British firm is making specially desigred agricultural equpment to suit Nigerian farmers and the first tools will be shipped in March.

Designed by Mr. A. R. Stokes, of Newton Tony, Wiltshire, who was for some time an agricultural research engineer working for the Nigerian Govenment, the equipment will be drawn by cattle (oxen).

It consists of multi-purpose tool frames into which numerous agricultural attachments can be fixed. The frames have draft bars and two legs to which shares and other cultivating equipment can be easily attached for ridge farming.

When Mr. Stokes returned to Britain from Nigeria, he and his brothers started their own engineering business with the sole purpose of manufacturing farming equipment special suitable for tropical climates.

## Johnson Discusses War On Poverty With Negro Leaders

WASHINGTON, — Four prominent Negro leaders went to the White House Saturday to discuss the adminisitration's planned all-out attack on poverty. The visitors were: Rev. Martin Luther King, head of the Southern Christain Leadership Conferenre; James Farmer, head of the Congress of Recial Equlity (CORE) Roy Wilkins, executive Secretary of the National Association for the Advancement of of Colored People (NAACP), and Whitrey Young, excutive director of the National Urban League.

After their one hour meeting with President Johnson, Dr. King told newmen, "most of the discussion centered around ways and means to mobilize support for the war on poverty. He added there was some talk about civil rights, but it was, incidental to the purpose of the conference.

Dr. King said he and the other leaders, as well as President Johnson hope the civil rights bill will rach the House of Representatives for debate by the end of January.

He said he and the other Negro leaders were invited to the White House Saturday to discuss the forthcoming Presidential message on poverty. No date has been announced as to when it will be sent to Congress by President Johnson. The message is expected to spell out the legislation needed to implemet the antpoverty crusade.



### Nwon Yo Agbaje Ni Minisita ...

# Aiperi Wo Oro Awon Egbe Ala-kuko Ni Ibadan

IBADAN--Kaka ki ija otẹ ati tẹmbẹlẹkun ti awọn ọmọ ẹgbẹ Alakuko (NCNC) ilu Ibadan mba ara wọn ja dẹrọ nṣe ni o tun npele si, o dabi ẹni wipe aiperi fẹ wọ ọrọ wọn na lori irohin ti a tun gbọ loru ana wipe awọn alayọnuso kan ti nda sii.

Lẹhinti awọn olori ẹgbẹ na ti yan igbimọ afunnisọ mẹrin kan ni ilu Ibinni ti Ọgbẹni R O A Akinjide ti pe gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ na ti nwọn wa ni Ibadan, ti nwọn fanke kọri wipe awọn ko gba ki awọn Ibo ma wa jẹ gaba lori awọn, ni a gbọ wipe nṣe ni ọrọ ija wọn na tun nle si.

Oniroh n wa ni ọrọ ti Oloye R. A. Akinyẹmi ("ỌBẸ LAWỌ") da si ija na tun lẹ jẹkị aiperi wọ ọrọ ija wọn na. Akinyẹmi ni ki nwọn yọ Lọya Akinjide iṣẹgbẹ ti ko ba le gba aṣẹ ti awọn ẹgbẹ ba pa. Orukọ awọn ọmọ ẹgbẹ Ọpẹrẹ Okpara ni Akinyẹmi fi sọrọ na, ṣugbọn awọn ọmọ ẹgbẹ Okpara na na ni awọn ko ran ao nisẹ rara,

Agbaje ti nwọn gba iṣẹ minisita lọwọ rẹ ni ọsan ana ni Ibadan. A ko mọ nkan ti o fa a ti nwọn fi GBE IJO FUN MINISITA NA ṣugbọn a ro wipe gbogbo rẹ ko ni yẹ lori rudurudu ti o nṣẹlẹ ni Ibadan na lọwọ lọwọ nisisiyi.

A gbọ wipe Oloye Agbaje pa-apa soro lana wipe on lọwọ ninu ituka ti nwọn tu awọn Oloye ẹgbẹ Alakuko kan ni Ibadan, o ni on wa ni Ibinni nigbati nwọn nsọrọ na.



**Olola Akinfosile**

Olola Akinfosilẹ ewo ni ẹri sọ si ọrọ ija aiperi ti awọn ọmọ ẹgbẹ ALAKUKỌ yi?

## Agbaje Pade Agbako

Mo gbọ wipe awọn ara Ibadan ti tẹsẹ bọ ṣokoto wipe bi iwaju ko ba se iṣ awọn a pada sẹhin. Nwọn ni awọn lẹ ki nwọn niran biẹgbẹ Alakukọ na ti lẹ lọ ni Ibadan ni ọdun karun sẹhin.

Gbogbo awọn ọmọ Ibadan ti o wa ninu ẹgbẹ na ... nwọn si ṣe ... Oloye Akinyẹmi "Ọbẹ- ... wipe ti o ti bẹ ṣe ... awọn ni Ibadan lo ..., ko mọ iayipo, awọn ... o ba lẹ sọrọ ilu ki ... si Iodo-Awo ni Ekiti ... ki o lọ tun ... ṣe ... ma ṣe ala, ... si ọrọ awọn.

... pajawiri kan ti a ... gbọ ... ọrọ ija alaiperi awọn ọmọ ẹgbẹ Alakuko na ni ti ... alamojuto eto ... ijọba ..., ... Oloye ...

## Ara Olowogbowo

(O bere loju ewe kinni)

LEDB nitoripe nwọn ko ni enia to lọwọ ... ṣe eto lati wo gbogbo awọn ile ti o nbẹ ni Ebute ... Awọngbọn ... Alakoro ... owo ti awọn yio san fun awọn onile na.

A gbọ wipe awọn Oyinbo kan ti nwọn lọwọ ... wipe awọn ... ti lọ fojn kan Alhaji Musa Ya' Adua Minisita alamojuto eto ... Eko ti iwe eto kojẹ ... na wa lọwọ rẹ. Nwọn ni awọn le ṣe iṣọ na ni Lakaa.

# Ayiluka Ni:

## Ibo Ko Iwosi

(O bẹrẹ loju ewe karun)

### Okun Alasia

Awọn Aganyin ati awọn Yoruba ti nwọn ngbe Okun Alasia ti gba kamu-nwọn ti nko ẹru wọn ati ọmọ wọn gba ibomiran lọ, emi ko ti gbọ wipe Ijọba fun wọn ni epinni rara, boya nwọn le fun wọn ni owo iọla a ko le sọ.

### Onyiuke Fomo Yo

Mo gba fun Lọya G. C. M. Onyiuke tiṣe ọga agbẹjọro Ijọba ti o binu fiṣẹ silẹ nitori iwọsi ni Enugu, eni akọkọ ni ọrẹ mi, Lọya G C Nonyelu ti o binu fi iṣẹ agbẹjọro Ijọba Apapọ silẹ l'Eko nitori iwọsi ofin titun. Awọn Ibo kọ iwọsi.

Bi awọn Ibo ko ba kọ iwọsi ni ẹnyin ọkawe mi, kinni le mu Lọya Nonyelu ati Onyiuke fi iṣẹ agbẹjọro Ọba silẹ. Owo wa nibẹ, Ọla wa nibẹ, iwọsi ati ẹgbin oniyọrọ si tun wa nibẹ. Ọrọ pọ nibẹ ẹnyin ara mi.

### Eran Elede Awe

Igbẹ adiẹ ko dara ni Masalasi ṣugbọn o dara lori iresi sara; o ti pẹ ti awọn kan ma nsọ wipe ẹran ẹlẹdẹ ko tọna fun awọn Musulumi Imale lati jẹ ṣugbọn mo gbọ wipe ẹran ẹlẹdẹ na ni awọn iyawo oniyigi kan fi NSE ọbẹ sari awẹ fun ọkọ wọn ni Oke-Odo. E maṣe si mi gbọ, OKE-ODO BẸRẸ LATI OYINGBO, YABA, MAKOKO, SABO ATI ABULE-ỌJA ti o FI DE ABULE IJẸSHA. Boya a le ri awọn ẹran na lọdọ ẹnikọkan ni gbogbo ibiti mo darukọ wọnyi. Ti ẹ ko ba fẹ ki inu ruu yin tọmọtọmọ, ki ẹ ma ṣe jẹ ẹran ile idalẹun.

# Salamotu Feran Eran Elede

( O bẹrẹ loju ewe kinni )

awọn le danu sun wọn nitoripe nwọn ti pọ pupọ nile ti enia ba jẹ wọn nwọn le hu arun mi silẹ.

Ẹru ẹran ẹlẹdẹ ati ẹran oniyọ ti awọn Oyinbo onisowo na fi mọto akẹru ru lọ si ile-idalẹnu na ki ṣe yẹyẹ rara, ti nwọn ba fẹ ta wọn, nwọn a ri to ẹgbaaji pọnun ( £4,000 ) nibẹ.

Gbara ti awọn akọwe Wolewole ti bẹrẹsi ko wọn lọ si ile idalẹnu ni nwọn ti fi awọn ọlọpa sibẹ ki awọn ẹnikan ma le ko wọn lọ tapoti tapoti, ṣugbọn nigbati o di oru ni awọn ọkanjua enia ti o wa ni agbegbe ibiti nwọn ko awọn ẹru ẹran ẹlẹdẹ na lọ bẹrẹsi du wọn ti olukuluku obinrin pẹlu awọn ọmọ wọn nko eyi ti ọwọ wọn ba lọ sile wọn.

A gbọ wipe ninu awọn ẹran ẹlẹdẹ na pẹlu ọra wọn ti nṣe yoyo ni awọn obinrin ọkanjua na fi ṣe ọbẹ sari fun awẹ ti ọkọ wọn gba ni owuro ijẹta. A tun gbọ wipe nwọn ti nta ninu awọn ẹran na fun awọn ara Makoko ati abule Ọja, awọn Ọlọpa ọtẹlẹmuyẹn obinrin ati ọkunrin si ti nlọ sọja Sabo ati Oyingbo boya nwọn le ri awọn ẹran ati awọn ọja na nibiti nwọn gbe nkiri wọn kakiri.

Ẹ sọrọ pẹlu ẹran ti nwọn ṣa ninu ile idẹlẹnu o.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos
Phone 23370 Editor; (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos, P O Box 467,